# Ojúùwòye Yorùbá Lórí Ọ̀rọ̀ Ààbò Àti Ìfaradà Ẹ̀sìn Nínú Ìdàgbàsókè Orílẹ̀-Èdè

**Bísí Ògúnṣínà** ***Ph.D***
**(Ààrẹ Àná Ẹgbẹ́ Onímọ̀-Èdè Yorùbá)**
*Yunifásitì Ìpínlẹ̀ Èkìtì (Adó-Èkìtì)*

***Ọ̀rọ̀-Ìṣide Ìpàdé Gbogbogbòò ti Ẹgbẹ́ Onímọ̀-Èdè Yorùbá Ní Yunifásítì Ìpínlẹ̀ Èkìtì, Adó-Èkìtì, October 3, 2012***

Orí ọ̀rọ̀ fún ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí jinlẹ̀ púpọ̀. Ó sì wúlò fún ìtẹ̀síwájú ìran Yorùbá àti orílẹ̀ èdè. Mo gbàgbọ́ pé ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí yóò mú ìtẹ̀síwájú bá ìmọ̀ Yorùbá. Ìdí ni pé ó ní àsomọ́ tó nípọn pẹ̀lú ìmọ̀ Akiọ́lọ́jì, Lìngúísíìkì, ìbára-ẹni-gbé-pọ̀, ìmọ̀-ìjìnlẹ̀-èrò, ìmọ̀-ìtàn, ìsègùn, ẹ̀sìn àti ìṣẹ̀ṣe Yorùbá. Ìwádìí ìjìnlẹ̀ làti ọ̀dọ̀ àwọn Ọ̀jọ̀gbọ́n jìnrà-jìnrà bíi I.A Akínjógbìn, Adé Ọbáyẹmí, Abíọ́dún Adétugbo, J.A. Àtàndá, J.H Greeberg abbl, ti fi ẹsẹ̀ rẹ̀ múlẹ̀ pé kìí ṣe Arabia, Egypt, Nubia àti Meroe ni ìran Yorùbá ti ṣẹ̀ wá. Apá ìpàdé odò Ọya àti Benue ni ìwádìí fi ẹsẹ̀ rẹ̀ múlẹ̀ pé Yorùbá ti wá. Ọ̀jọ̀gbọ́n Akinjogbin fi kún un pé, sáájú Odùduwà, ó tó bíi Ọba mẹ́tàdínlọ́gọ́rùn ún tó ti jẹ ní Ilé-Ifẹ̀. Ohun tí èyí túmọ̀ sí ni pé, ọjọ́ pípẹ́, ọjọ́ tíanréré ni ìran Yorùbá ti ṣẹ̀. Wọ́n sì ní ọgbọ́n àti ọ̀làjú púpọ̀. Èyí ló mú kí àwọn Ọ̀jọ̀gbọ́n àti ọ̀mọ̀ràn gbà pé Yorùbá jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn ìran ènìyàn tó lajú jù lóde ayé yìí.

Ọgbọ́n àti ìṣẹ̀ṣe Yorùbá dá wọn lójú tó bẹ́ẹ̀ gẹ́ẹ́ tó fi jẹ́ pé ibikíbi tí wọ́n bá wà, gbọgbọọgbọ lọwọ́ ń yọ ju orí ni ọ̀rọ̀ wọn máa ń jẹ́. Pierre Verger (1960) jẹ́rìí sí èyí nígbà tí ó sọ pé:

> *. . . the Yoruba, known in Brazil under the name of Nago and in Cuba under that of Lucumi, conserve their traditions better than any other African peoples . . . They have not only remembered their language but also their traditional songs, their musical instruments, their dances, and their attitude towards their ancestors' spirits . . . They prepare their culinary specialities which are none than the classic àkàrà, ọ̀ọ̀lẹ̀, ẹ̀kọ, amala and other dishes prepared with palm oil as a base.*

Ọwọ́ tí wọ́n fi mú ọgbọ́n, ọ̀làjú àti ìṣẹ̀ṣe wọn lásìkò òwò ẹrú ni àyọlò yìí ń ṣọ. Lẹ́yìn tí wọ́n bọ́ kúrò nínú ìdè òwò-ẹrú, wọn kò jẹ́ kí ọ̀làjú òyìnbó gba ìṣẹ̀ṣe wọn lọ́wọ́ won. Fálọlá (2012:28) fi ẹnu rẹ̀ jóná, pé:

> *When they became free, adaptations to economic circumstances dictated learning new trades and crafts. Thus in Cuba and Brazil, we had Yoruba as shoemakers, tailors, barbers, hawkers, etc. They formed guilds and constructed economic network such as the Èsúsú method which enable them to save and invest. They respected the successful among themselves. In the case of Bahia, a number of streets were named after Yorùbá while freedmen and women who*

*clustered together lived in such a place as Nagotedo (Nago-established), a way of claiming their ownAutonomous space.*

Kò sí àní-àní pe àyọlò yìí fi orí-pípé àti ọgbọ́n-inú, ìtẹpámọ́ṣẹ́ àti àròjinlẹ̀ Yorùbá hàn láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀. Fálọlá (2012) tún sọ síwájú síi pé;

> *The Yorùbá were not the most numerous, they were the latest to arrive in America but they were the greatest and most remarkable in influence. The impact of Yorùbá remains uncontested. The dominance of Yorùbá culture has led to Yorubaism.*

Ohun tí àyọlò ń fi ẹsẹ̀ rẹ̀ múlẹ̀ ni pé "ọ̀run lòsùpá ti múyì wáyé" ní ọ̀rọ̀ ọgbọ́n ìjìnlẹ̀ àti orí-pípé Yorùbá. Olóyè I.O. Délànọ̀ (1957) ṣe àlàyé ó ní: "Lí ọjọ́-wọ̀n-ọn-nì, lí àsìkò tiwa, ayé rójú, àlàáfìà wà, óúnjẹ pọ̀". Olóyè Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ (1968:6) náà jẹ́rìí síi, ó ní; *The Society into which I was born was an agarian and peaceful society.* Ohun tí àwọn méjèèjì ń fúnka mọ́ ni pé láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ ni ìran Yorùbá ti jẹ́ ìran tó fi àlàáfìà àti ààbò tó péye ṣe ìpìlẹ̀ ilé, ìlú àti àwùjọ wọn. Ìbéèrè tó wúlò ni pé: kí ni wọ́n fi ń ṣe é? Báwo ni wọ́n ṣe ń ṣe é?

## Ojúùwòye Ààbò Ní Ilẹ̀ Yorùbá

Ohun àkọ́kọ́ tí a ní láti fi ẹnu rẹ̀ jóná ni pé, láti ìpilẹ̀ṣẹ̀ ni Yorùbá ti jẹ́ ìran amèètò-ṣèètò, amẹ̀tọ́ṣẹ̀tọ́, amọ-ire-ṣe-ire àti

Ọmọlúàbí. Nínú gbogbo abala ìṣèlú, ìbára-ẹni-gbé-pọ̀, ìmọ̀-ìjìnlẹ̀-èrò àti ọ̀rọ̀ ẹsìn, kò sí èyí tí wọn kò gbé kalẹ̀ létòlétò. Típẹ́tipẹ́ sì ni ètò wọn so mọ́ ọ̀rọ̀ ààbò. Ọ̀jọ̀gbọ́n Bọ́lájí Ìdòwú (1955:5) ṣe àlàyé ó ní:

> *In the main, the Yorùbá claim to be descendants of a great ancestor. There is no doubt at all, that they have been a great race. Indeed, they are the progeny of Great War lords, efficient kingdom builders and astute rulers. They have been enjoying for centuries a well organised pattern of society, a patternwhich persists basically in spite of all the changes consequent upon modern contacts with the Western World. Their Kings have, from a very long past, worn costly beaded crowns and wielded royal scepters. And no one remembers a time when the Yorùbá have not worn clothes. Truly, then, they have their reasons for being proud of their race.*

Ẹrí àrígbámú ni pé yàtọ̀ sí pé ọmọ akin ni ìran Yorùbá láti ìbẹ̀rẹ̀ ayé wọn, wọ́n tún jẹ́ ọmọ akọni-lógun, tó mètò tí à á fi tòlú tí fi i tùbà tùṣẹ. Ìjì àyípadà gan-an tó tipasẹ̀ àjọṣepọ̀ pẹlú àwọn òyìnbó wàyé kò bí ọ̀làjú àṣà ìwọṣọ olówó-iyebíye lóní-ran-ǹ-ran tí tọba tìjòyè ìlú ń lò láti dáàbò bo ara wọn. Yorùbá kò fi ọwọ́ yẹpẹrẹ mú ọ̀rọ̀ ààbò. Yorùbá ní èto ààbò tó kira, tó sì nírogbo: Ààbò ara-ẹni, ààbò ilé, ààbò iṣẹ́, ààbò àdúgbò àti ààbò ìlú.

**Ààbò fún Ọmọdé**

Onírùrúurú ọ̀nà ni Yorùbá ń gbé ọ̀nà ààbò gbà ní àwùjọ wọn. Ẹ jẹ́ kí á ṣe àgbéyẹ̀wò ààbò fún ọmọdé. Láti inú oyún ni Yorùbá ti máa ń ṣe ètò ààbò fún ọmọ. Bí oyún bá ti dúró nínú obìnrin ni wọn yóò ti ṣètò ààbò fún ọmọ náà. Ààbò àkọ́kọ́ ni díde oyún mọ́ inú ìyá rẹ̀ kí oyún náà má le bàjẹ́ tàbí kí ó jábọ́. Àwọn babaláwo tàbí oníṣègún ni wọ́n máa ń ṣètò ìdeyún yìí, wọ́n gbàgbọ́ pé oyún náà yóò wà ní àlàáfíà nínú ̀ìyá rẹ̀ títí ọjọ́ ìbímọ, onírúurú oògùn ni wọ́n máa ń ṣe sí ọmọ lára gẹ́gẹ́ bíi ààbò fún ọmọ náà. Lára rẹ̀ ni: Àgbo wọ́bọ́, àgbo jẹ̀díjẹ̀dí, àgbo joríjorí, àgbo gìrì, àgbo eyín, abbl. Ó fẹ́rẹ̀ jẹ́ pé gbogbo àìsàn tó máa ń ṣe ọmọdé ni àgbo wà fún. Bí ọmọ bá ti ń dàgbà, wọ́n le so nǹkan mọ́ ọn lọ́wọ́, lẹ́sẹ̀ tàbí lọ́rùn; áájò ààbò ẹ̀mí gígùn àti àìkúléwe ló jẹ́ fún ọmọ náà. Èyí túmọ̀ sí pé, àjẹbí ni ọ̀rọ̀ ààbò fún ọmọ Yorùbá.

**Ààbò Ara Ẹni**

Ojú ni alákàn fi ń ṣọ́rí ni ọ̀rọ̀ ààbò ara ẹni. Kójú má ríbi àìjáfara ni oògùn rẹ̀. Yorùbá kò fi ààbò ara ẹni jáfara rárá. Onírúurú aájò àti oògùn ni wọ́n fi ń ṣààbò ara wọn. Lára àwọn oògùn bẹ́ẹ̀ ni kánàkò èyí tó le sọ ìrìnàjò tó le gba ọ̀sán mẹ́ta òru mẹ́ta di ọjọ́ kan péré láìsí ewu. Nínú aájò fún ààbò ni òkígbẹ́, tó jẹ́ pé bí wọ́n bá sá wọn ládàá kò ní ràn wọ́n, tàbí kí àdá yẹn dá sọnù.Wọ́n máa ń lo ìfúnpá àti óńdè. Nígbà míràn, wọ́n le lo

àgbékọ̀rùn pẹ̀lú dàńsíkí àti fìlà; egbé nìyẹn. Bí àpẹẹrẹ, láyé àtijọ́ Aláàfin Ọ̀yọ́ gbọ́ pé Ọba ìlú kan, ìyẹn Òkukù ní ìpínlẹ̀ Ọ̀ṣun, ní oògùn púpọ̀. Aláàfin pàṣẹ pé kí ó wá fi ojú kan òun. Bí ó ti dé ààfin ni wọ́n sọ fún un pé kí ó jókòó lórí ẹní. Kò mọ̀ pé wọ́n ti gbẹ́ kòtò jínjìn sábẹ́ ẹní. Bó ṣe jókòó ni ẹní jìn fìn-ìn. Ó kégbe ńlá "hèéè !". Kíké tó ké, inú iyàrá rẹ̀ ní ààfin rẹ̀ ló bá ara rẹ̀ lÓkukù. Egbé nìyẹn. Ààbò tó péye ló jẹ́ láàrin àwọn Yorùbá.

Òrùka ẹ̀rẹ̀ tún jẹ́ ààbò tó pàtàkì. Bí wọ́n bá fi òrùka àlùwó lu ènìyàn, bó ti wù kí olúwa rẹ̀ tóbi tàbí ga tó, ilẹ̀ ni yóò bá ara rẹ̀. Ní ìgbà mìíràn, bí wọn bá fi òrùka gbá ènìyàn létí, lójijì agbọ́n yóò ṣẹ́ létí ẹni náà. Dàámú, dààbo yóò sì bá àwọn ọ̀tá, wọn yóò sì túká. Wọ́n tún lè lo ọrẹ́ tí wọ́n ti rẹ láti fi lu ọ̀tá, yóò ṣubú yakata ni. Gbẹ́rẹ́ sínsín jẹ́ ara ààbò ara ẹni. Onírúurú gbẹ́rẹ́lówà. Wọ́n lè sín ọ̀kan-lé-rúgba (201) gbẹ́rẹ́ tàbí ọ̀tà-lé-nírinwó-ó-din-mẹwàá (450) gbẹ́rẹ́ láti iwájú dé ẹ̀yìn. Ààbò náà ni. Ààbò tó lágbára.Wọ́n a máa so àdó mọ́ra tàbí mọ́ ọrùn, ààbò lọ́wọ́ àwọn iwin, ẹbọra tàbí ẹ̀rù òru, ọfà tí ń fò ní ọ̀sán, àjàkálẹ̀ àrùn tí ń rìn kiri ní òkùnkùn tàbí ìparun tí ń runni lọ́sàn-an gangan.

Onírúurú ọfọ̀, ààsán, àfọ̀ṣẹ abbl ni ń bẹ lẹ́nu Yorùbá láti dá ààbò bo ara wọn. Bí àpẹẹrẹ;

> Arọ ni mí, wọn kìí bú mi
> Aràrá ni mí, wọn kìí lù mí

Abuké Onírá ni mí
Ẹ má ha mi lokun
Ni ni gan-in gan-in sálesale
Ọ̀nà mo rìn, mo pàdé ayọ̀
Ọ̀nà mo rìn mo pàdé
Olórìṣa ńlá tòun tèkó ori
Ọ̀nà tí mo rìn lónìín
Má jẹ́ kíbi ó pàdé mi o
Dédé ire ni kí n ṣe

Ọfọ̀ àkòyà-ibi, àrìnnàkore ni èyí. Irú wọn pọ̀ lẹ́nu Yorùbá láti máa fi sàábò lórí ara wọn. Ìṣújú ń kọ́ àti àfẹ́ẹ̀ri, kí ọ̀tá má le è rí wọn, kí ààbò kó bò wọ́n, kí iyè ọ̀tá ó rá. Lásìkò ìjà ìgboro tàbí láàrin àwọn olè, ẹni tó bá lo àfẹ́ẹ̀rí, kò sí ẹni tó máa rí i títí yóò fi kọjá láàrin wọn.

### Ààbò Ilé

Yorùbá kò fi ilé wọn jáfara. Nítorí náà, ètò wà fún ààbò ilé láwùjọ wọn. Onírúurú ni ètò ààbò yìí. Láyé àtijọ́ bí Yorùbá bá fẹ́ la ẹṣẹ̀ ilé, igun mẹ́rẹ̀ẹ̀rin ni wọn yóò ri nǹkan mọ́. Lára ohun tí wọ́n máa ń rì mọ́lẹ̀ ni ìgbín àti ewé akòko. Ẹ̀rọ̀ pẹ̀sẹ̀ ni tìgbín, ọ̀wọ̀ sì wà fún ewé akòko. Àmì ìfinijoyè ni, kì í sì í rọ bọ̀rọ̀bọ̀rọ̀. Bí wọ́n bá kọ́lé tán, wọn yóò fi àsokọ́ sí ẹnu ọ̀nà àbáwọlé, òṣùṣù-ọwọ̀ pẹ̀lú owó ẹyọ ni wọn yóò fi sí àtẹ́rígbà ilé. Kò sí baba olè tó le jalè nínú ilé bẹ́ẹ̀. Ní kété tí olè bá ti wọlé ni òṣùṣù-ọwọ̀ tí wọ́n so sókè yóò jábọ́ sílẹ̀. Ní kíá ni iyè olè yóò rá.

Ó le mú ọwọ̀ kí ó máa gbálẹ̀ tàbí kí ó máa pa ràdìràdì lójú kan títí ilẹ̀ yóò fi mọ́ bá a.

Ẹ̀wẹ̀, wọ́n le so ìgò kọ́ sí ẹnu ọ̀nà àbáwọlé, wọn yóò rọ ìtọ̀ àti nǹkan mìíràn sínú rẹ̀. Bí olè bá ti wọlé, yóò di aláìlágbára. Ní ìgbà mìíraǹ wọ́n le so àdó mọ́ ẹnu ọ̀nà àbáwọlé, kí olè má le wọlé. Ọgbọ́n mìíràn ni kí wọ́n bo orù mọ́lẹ̀ pẹ̀lú ìfun òkété àti nǹkan mìíràn.

Kò sí olè tí yóò le wọlé. Níwájú ilé mìíràn, Èṣù ni wọn yóò rì sí ẹ̀bá ẹnu ọ̀nà láti máa dá ààbò bo ilé. Ìdí èyí ni wọ́n fi máa ń sọ pé;

Baálé, Baále
AbÉṣù lóde
Èyí tí ò lÉṣù lóde
Abọ̀rọ̀ Èṣù lọ́rùn

Èyí túmọ̀ sí pé, baálé tí kò bá ní Èṣù níwájú ilé rẹ̀, ọ̀rọ̀ bí Èṣù bí Èṣù kò jìnà sí ilé rẹ̀.

## Ààbò fún Iṣẹ́ Ẹni

Akínkanjú àti igi-iṣẹ́ ni Yorùbá. Ọmọ oníṣẹ́ ni ìran Yorùbá. Oníṣẹ́ ni baba-ńlá wọn ṣe. Iṣẹ́ àgbẹ̀ ló gbòòrò jù nílẹ̀ Yorùbá. Kò sí ibi tí wọn kì í tí kádìẹ alẹ̀ ni ọ̀rọ̀ iṣẹ́ àgbẹ̀ ní ilẹ̀ Yorùbá. Wọn kì í fi ọ̀rọ̀ oko wọn ṣeré. Wọ́n ní ètò ààbò fún oko wọn. Lára ètò ààbò wọn ni ọ̀nà yíyán. Wọ́n yóò bu egbò igi sínú omi, wọn yóò wọ́n ọn sínú oko wọn, nípa èyí olè kò ní le dé ọ̀nà oko yẹn.

Ọ̀nà mìíràn ni fífi ejò sọ́ oko. Bí olè bá ti wọ inú oko, ejò ńlá ràpàtà ni yóò yọ sí i. Bí ó bá lo agídí, ejò yóò lé e. Bí ejò yẹn bá sì bu olè náà jẹ, ọ̀run lẹ̀rọ̀. Ọ̀gá ilé-ìwé kan lo ọgbọ́n náà fún ilé-ẹ̀kọ́ rẹ̀. Ejò ló ń ṣọ́ ilé-ẹ̀kọ́ náà. Olèkólè tó bá wá sí ilé-ẹ̀kọ́ náà, ejò yóò yọ sí i, bí olè bá sì ti rí ejò ni olè yóò họ.

Àwọn àgbẹ̀ a máa ri Èṣù sí ojú ọ̀nà oko wọn. Olè tó bá ti rí Èṣù lójú ọ̀nà tàbí àlà oko yóò mọ̀ pé ewu ń bẹ lóko Lóńgẹ́, Lóńgẹ́ fúnra rẹ̀ ewu ni. Bákan náà, wọ́n a máa pààlè lé ohun ọ̀gbìn wọn nínú oko láti dẹ́rù ba olè. Síwájú sí i, wọn a máa dẹ tàkúté "ẹni-èèràn". Èyí ni tàkúté ńlá tó le mú odidi ènìyaǹ mọ́lẹ̀ tí kò sì níí lè yọ. Tàkúté ẹni-èèraǹ yìí wà láti mú olè nínú oko.

## Ààbò Àdúgbò

Ní ilẹ̀ Yorùbá, àkójọpọ̀ àdúgbò ló ń jẹ́ ìlú. Àdúgbò kọ̀ọ̀kan ló si ní olórí. Ohun tó sì ń jẹ olórí àdúgbò lógún jùlọ ni àlàáfíà àti ààbò àdúgbò. Kò sí ohun tó ń ṣẹlẹ̀ ní àdúgbò tí olórí kò ní mọ̀. Bí àlejò kan bá dé sí ilé kan ní àdúgbò kan, àwọn ọ̀tẹlẹ̀múyẹ́ wà tí yóò ta olórí àdúgbò lólobó. Bí àlejò kan bá dé àdúgbò, kò ní pẹ́ tí olórí àdúgbò yóò fi mọ̀. Àwọn aládùúgbò mọ ara wọn. Ní àdúgbò kọ̀ọ̀kan, àjọtọ́ ni ọmọ. Ẹnìkan ní í bí ọmọ gbogbo àdúgbò ní í wò ó. Ìbáwí kò pin sọ́dọ̀ òbí nìkan. Bí ọmọ bá ń hu ìwà burúkú kan, kò ní rí ibi dúró sí ládùúgbò. Olè àdúgbò kò le sápamọ́ ládùúgbò. Olè àdúgbò kò le rí aya fẹ́. Kíá

ni àdúgbò yóò tú àṣírí pé "olè ni o fẹ́ fọmọ fún". Ara ààbò ni. Bí ọmọbìnrin bá lóyún oge, ọ̀ràn dé. Ìtìjú ńlá ni fún àwọn òbí rẹ̀. Etí ìyá rẹ̀ yóò gbọ́ pásapàsa ọ̀rọ̀. Bí ìyá ọmọ bẹ́ẹ̀ bá lọ jẹ́ ààyo ọkọ, àwọn orogún rẹ̀ yóò fi ojú tìyátọmọ rí mọ̀bo! Àtirọ́kọfẹ́ irú ọmọ bẹ́ẹ̀ yóò di ọ̀ràn. Irú àjọgbépọ̀ tó níye lórí báyìí, ara ọgbọ́n ààbò Yorùbá ni.

Nínú àdúgbò, alágbẹ̀dẹ gbọ́dọ̀ mọ iye ọmọ tó ń kọ́ṣẹ́ lọ́dọ̀ rẹ̀. Ó gbọ́dọ̀ mọ̀ wọ́n tilétilé. Ó gbọ́dọ̀ mọ ìrìn wọn àti ìwà wọn. Bí wàhálà kan bá ṣẹlẹ̀ ládùúgbò, kò ní ṣòro láti mọ ọ̀dádá tó dá wàhálà sílẹ̀. Ìdí ni pé wọ́n mọ ara wọn dáadáa.

## Ààbò fún Gbogbo Ìlú

Nínú ọ̀rọ̀ ààbò ìlú ni ọgbọ́n ìṣèlú Yorùbá ti farahàn jù lọ. Kí Yorùbá tó tẹ ìlú dó, ifá gbọ́dọ̀ lọ́wọ́ sí i. Ó sì ní irú ètùtù àti ẹbọ tí wọn yóò rú fún àlàáfíà àti ààbò ìlú. Ẹbọ rírú àti ètùtù yìí, ara ààbò ni. Ìtẹ̀dó ìlú máa ń ní ọwọ́ àwọn Babaláwo nínú. Ó máa ń ní oògùn tí wọn yóò rì mọ́lẹ̀ tí ogun kò fi ní wá kó ìlú wọn. Èyí jẹyọ nínú orin ìbílẹ̀ kan;

> Mo dénú ọkọ̀, mo simi,
> Mo dénú ọkọ̀, mo simi,
> Ogun ò jà ja, kó kó Ògbómọ̀ṣọ́ rí,
> Mo dénú ọkọ̀, mo simi,

Ó ní ohun ìjìnlẹ̀ tí àwọn Baba-nlá àti àgbà àwo ṣe tí ogun kò fi kó Ògbómọ̀ṣọ́ àti àwọn ìlú mìíràn ní ilẹ̀ Yorùbá.

Ìtẹ̀dó ìlú ara ààbò ni. Bí àpẹẹrẹ, ìlú Mọ̀pà ní ìpínlẹ̀ Kogí, ọ̀nà méjì ni wọ́n pín sí. Ilẹ̀-tẹ́jú, orí-òkè ni wọ́n tẹ̀dó sí fún ààbò. Àwọn òyìnbó ló lé Ilẹ̀-tẹ́jú sọ̀kalẹ̀ nítorí ìṣòro ńlá tó jẹ́ fún wọn láti máa gbé Haamọku gorí òkè. Àlááfià pọ̀ fún àwọn, Ilẹ̀-tẹ́jú lórí òkè tí wọ́n wà. Àwọn apá kejì wọn ni Odò-ilẹ̀. Inú ihò ń lá kan ni wọ́n tẹ̀dó sí fún ọ̀pọ̀ ọdún, nítorí ààbò náà ni. Ọgbọ́n Yorùbá pọ̀!

Ọ̀pọ̀ ìlú ló mọ odi yí ara wọn ká. Odi yìí ni wọ́n fi ṣe ààbò wọn. Lẹ́nu odi ilú ni oníbodè wà. Oníbodè ló dàbí ẹ̀ṣọ́ ilú tí yóò máa ṣe àkóso àtiwọlé àti àtijáde àwọn ènìyàn. Ẹni tó bá fura sí pé ó le ṣe ilú níbi tàbí ẹni tó bá lẹ́bọ lẹ́rù tó jẹ́ eléwù ènìyàn, oníbodè kò ní jẹ́ kó wọlé. Oníbodè kìí dá dúró, Èṣù yóò wà lẹ́gbẹ rẹ̀ tí wọ́n rì mọ́lẹ̀. Èṣù yìí ni yóò máa lé ibi dànù lẹ́nu ọ̀nà ìlú. Ààbò pàtàkì ni Èṣù jẹ́ fún ìlú. Alóre máa wà lórí odi ìlú. Òun ni yóò jẹ́ kí ilú mọ bi ogun tàbí ọ̀tá bá wà nítòsí tàbí jìnnà réré. Amí yóò jinna sí Alóre. Amí ni yóò máa tú àṣírí ọ̀ta. Ó máa ń ní orin àṣírí tí yóò máa kọ fún ọmọ ogun ilú láti tawọ́n lólobó ohun tó bá ń ṣẹlẹ̀. Amí tó bá gbọ́n lè mọ orin àsírí àwọn ọ̀tá tí wọn kò fi ni fura sí i títí yóò fi dé ọ̀dọ̀ wọn ti wọn yóò sì rò pé ara wọn ni.

Ààbò pàtàkì fún ilú kọ̀ọ̀kan ni ọmọ ogun ilú tó máa ń jà fún ìlú. Àwọn yìí ni ọdẹ tó lágbára tí wọ́n sì ní oògùn láti bá ọ̀tá jà. Onírúurú ọgbọ́n ni wọn lò làti dá ààbò bo ìlú. Ìlú máa ń gbẹ́ kòtò tí a tún ń pè ní yàrà yìí ìlú ká. Ní ìlú Ọ̀wọ̀, yàrà mẹ́rin ló yí

ílú yi po, èyí mú kí ó ṣòro fún ogun ọ̀tá láti wọ ìlú wá. Ohun mìíran ti àwọn ọdẹ àtí awo máa ń lò fún ààbò ìlú ni májèlé. Wọ́n lè fi májèlé sí oúnjẹ ti wọn yóò sì gbé e sójú ọ̀nà. Bí ọ̀tá bá ti jẹ oúnjẹ náà, wọ́n le kú tàbí kí wọ́n di aláìlágbára. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, lásìkò tí àwọn Àdó(Bìnní ni wọ́n ń pè bẹ́ẹ̀) dòjú ogun kọ Ọ̀wọ̀, ọdẹ kan gbin abàmì ọ̀gẹ̀dẹ̀ sí etí ọ̀nà tí Àdó yó gbà wọ Ọ̀wọ̀. Ọ̀gẹ̀dẹ̀ náà hù lóòjọ́, ó sì pọ́n lóòjọ́. Bí àwọn Àdó ti rí Ọ̀gẹ̀dẹ̀ náà, inú wọn dùn, wọ́n sì jẹ́ ẹ́ ní àjẹgbádùn. Ní kété tí wọ́n jẹ ẹ́ tán ni wọ́n bá kọjú ìjà sí ara wọn, tí wọ́n sì lu ara wọn pa. Ìṣẹ̀lẹ̀ yìí ló fa orin ìbílẹ̀ tí àwọn Ọ̀wọ̀ ń kọ nígbà náà pé;

> Àdó gbógun wọ̀wọ̀,
> Ọ̀wọ̀ pa Àdó,
> Àdó fi lé baba rẹ̀ ṣogun jà.

Ohun tí orin yìí ń sọ ni pé, Àdó gbé ogun wá sí Ọ̀wọ́. Àwọn Ọ̀wọ̀ pa Àdó. Àdó kọjú ìjà sí ara wọn. Wọ́n fi ọmọ bàbá wọn ṣe ogun jà. Irú ọgbọ́n ìṣẹ̀gùn yìí pọ̀ lóríṣìíríṣìí jákèjádò ilẹ̀ Yorùbá tí wọ́n fi ń ṣe ààbò láti ṣẹ́gun ọ̀ta.

## Ọdẹ Aṣọ́de

Ó fẹ́rẹ̀ẹ́ má sí ìlú Yorùbá láyé àtijọ́ tí kò ní ọdẹ aṣọ́de. Tó bá ti di nǹkan bí aago mẹ́sàn-àn alẹ́ ni ọdẹ yóò ti gbòde. Wọn yóò máa lu ìlù ọdẹ ti wọ́n n pè ni "aféré". Iṣẹ́ tí wọn ń fi ìlù yẹn rán sí gbogbo aládùúgbò ni pé : ki onílé ó gbélé. Wọ́n tún máa n

fọn féré ọdẹ tí a mọ̀ si "ekùtù". Bí àwọn èèyàn bá ti gbọ́ ìlú aféré àti fèrè ekùtù, ọ̀rọ̀ di bó-ò-lọ-o-yà-fún-mi. Olè tí wọ́n bá mú lóru, onírúurú itú ni wọ́n lè fi pa, wọ́n le ní kó máa polówó ọjà káàkiri ìgboro tí yóò sì di ẹni ìtìjú àti ẹni àbùkù. Ní ìgbà mìíràn, wọ́n lè nàá ní ọrẹ́ oògùn, olè tí wọ́n bá nà bẹ́ẹ̀, ọ̀run lẹ̀rọ̀. Wọ́n lè pa olè mìíràn sí àpasára. Èyí ni pé kí wọ́n mú ìṣó ń lá tó tóbi tó sì gùn, kí wọ́n sì kàn àn mọ́-ọn lórí. Irú olè bẹ́ẹ̀ yóò joró kú ni.

Ní ìlú Ìkìrun ní Ìpínlẹ̀ Ọ̀ṣun, alágbára ọkùnrin kan tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ Àládòkun Ìyàndá ló máa ń ṣọdẹ lóru. Òun nìkan ṣoṣo ló ń ṣọ́ ìgboro Ìkìrun. Kìí ṣe ọdẹ, àmọ́ abàmì ẹ̀dá kan ni. Gaga ọwọ̀ kan ló máa ń mú dání tí yóò sì máa rìn káàkiri ìgboro. Ọ̀kan nínú agbára tó máa ń bò ni aríhiín-rọ̀hùún. Bí olè kan bá ti n runlẹ̀ ní àdúgbò Òkè-Aáfọ̀ ni Àládòkun yóò ti rí i, yóò sì sọ pé, "ìwọ taa nù un o?" Bí olè runlẹ̀ ní Okè-bà tàbí Òkè Ọbaàgùn, kíá ni Àládòkun yóò ti sẹ̀ ẹ́ pé "ìwọ wo nùn-un o"? Kíá ni olè yóò fẹsẹ̀ fẹ́ ẹ. Ààbò nlá ni Àládòkun Ìyàndá jẹ́ fún ìlú Ìkìrun. Òkìkì rẹ̀ sì kàn káàkiri gbogbo agbègbè Odò-Ọ̀tìn, Ìrágbìjí, Òṣogbo abbl.

Àjọṣepọ̀ tó gbọn-n gbọ́n ló wà láàrin àwọn ọdẹ, awo àti Ọba ìlú. Gbogbo àlọ́ àti àlọ̀ àjọṣepọ̀ náà, orí ààbò àti àláàfíà ìlú ló dá lé. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, ni Èkìtì, bí àlejò kan bá ti wọ̀lú, kò ní pẹ́ tí Ọba ìlú yóò fi mọ̀. Wọn yóò béèrè ibi tó ti wá, iṣẹ́ tó ń ṣe àti ohun tó wa ṣe. Àwọn ọ̀tẹlẹ̀múyẹ́ Ọba ń bẹ ní ìgboro láti sọ ohun tó ń ṣẹlẹ̀ káàkiri fún Ọba. Ìdí èyí ni wọ́n fi máa ń pa á lówe pé

”Etí baba nílé, etí baba lóko, ènìyàn ló ń jẹ́ bẹ́ẹ̀”. Ìṣẹ̀lẹ̀ burúkú kan sẹlẹ̀ ni ìlú kan ní Èkìtì, ọmọ méjì dédé sọnù nígboro. Wọ́n ṣe títí wọ́n kò rí wọn. Ní kọ̀pẹ́-kọ̀pé, ọmọ mìíràn tún ṣe ráá-ràà-rá ó rá. Kíá ni Ọba ke ́si olóri awo láti béèrè lọ́wọ́ Ifá. Ifá sọ pé, ọmọ méjì àkọ́kọ́ ti kú àmọ́ ẹ̀kẹta wà láàyè. Bí wọ́n bá wá a,wọn yóò rìi. Ní ẁarà-ǹ-ṣe-sà, Ọba tí ránṣẹ́ sí olórí ọdẹ. Gbogbo ọdẹ wọ inú igbó lọ, wọ́n sì rí ọmọ náà ní ibi tí wọ́n dè é mọ́, tí wọ́n fẹ́ yọ ojú rẹ̀ láti fi ṣe oògùn owó. Wọ́n mú àwọn àṣebi náà. Wọ́n sì gba ọmọ náà lọ́wọ́ wọn. Wọ́n mú àwọn àṣebi náà lọ sí ààfin. Ọba sì pàṣẹ pé kí á lé wọn kúrò ní ìlú. Èyí jẹ̀rìí sí i pé Yorùbá kò fi ọ̀rọ̀ ààbò falẹ̀, ẹni tí aje ìwà ìbàjẹ́ ba ṣí mọ́ lórí, wọn ò ní gba rìbá, wọn kò ní gba àbẹ̀tẹ́lẹ̀ títí wọn yóò fi mú un dé ààfin Ọba. Èyí ló mú kí àlàáfià wà láàrin ọ̀pọ̀ ilú kó tó di pé ọ̀rọ̀ ọ̀làjú dé sí ààrin wọn.

## Ẹsìn Gẹ́gẹ́ bí Orísun Ààbò

Bí ìgbà tí kánún já aásà ni ọ̀rọ̀ ẹ̀sìn jẹ́, ìṣe àti àṣà Yorùbá. Yorùbá ní ìgbàgbọ́ tó le nínú òrìṣà wọn. Wọn kò fi ọ̀rọ̀ Ṣàngó, Ògún àti Èṣù ṣeré. Tó bá di ọ̀rọ̀ ààbò, gbogbo ọ̀nà ni wọ́n máa ń gbà dẹ́kun ọ̀rọ̀ olè. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, bí ẹni kan bá jalè tí wọ́n sì mú un, tó bá ti di àsìkò ọdún ìbílẹ̀, àwọn obìnrin yóò máa kọrin ká lóru, wọn yóò sì máa dárúkọ olè náà, wọn yóò sì máa fi ṣe

yẹ̀yẹ́. Òkìkí ìwà ìbàjẹ́ yìí yóò kó ẹ̀tẹ́ àti àbùkù bá àwọn ará ilé olè náà, kò sí ẹni tí yóò fẹ́ fọmọ fún ìdílé olè.

Síwájú sí i, bí ẹnìkan bá jalè tí ó bá sọ pé òun kọ́, wọ́n lè mú¸un lọ sí ìdí Ògún pé kí ó wá ṣẹ́ èpè. Kò sẹ́ni tí yóò fẹ́ ṣẹ́ èpè níwájú Ògún. Irú èyí máa ń káwọ́ ìwà ìkà láwùjọ. Ilé kọ̀ọ̀kan ló ní òrìṣà tí wọ́n ń sìn, Wọ́n sì ní ìgbàgbọ́ tó le nínú òrìṣà wọn. Èyí ni àwọn ọdẹ fi máa ń kọrin pé;

> Ẹni rán ni lájò,
> Ní wolé de ni,
> Ògún náà ni yóò
> Wolé de ọdẹ.

Wọ́n gbàgbọ́ pé bí àwọn kò tilẹ̀ sí nílé, Ògún wà nílé yóò sì wolé dè awọn. Ó ní ẹbọ àti ètùtù tí wọn yóò ṣe fún Ògún kí wọ́n tó kúrò nílé.

Àwọn tí wọ́n ń sin Ẹ̀ṣù ní ìgbàgbọ́ tó ga nínú Ẹ̀ṣù pé alágbára ni, kìígbọ́ ki gbà ni. Ìdí èyí ni wọn fi ń fi Ẹ̀ṣù ṣọ́ ẹnu ọ̀nà ìlú, oko àti ilé fún ààbò. Lára orin tí wọ́n máa n kọ ni pe;

> Ẹ̀ṣù má ṣe mí,
> Ọmọ ẹlòmí-ìn,
> Ni o ṣe
> Onílé oríta,
> Ọmọ ẹlòmí-ìn,
> Ni o ṣe.

Kókó ohun tó wà nínú orin yìí nip é àwọn tí wọ́n n sin Ẹ̀ṣù, Ẹ̀ṣù kò gbọdọ̀ ṣe wọ́n, ọmọ ẹlòmíràn tí kò rúbọ fún Ẹ̀ṣù ni kí Ẹ̀ṣù ó ṣe.

Àwọn oníṣàngó ní ọgbọ́n ìjìnlẹ̀ tí wọn yóò fi pe ààrá sọ̀ kalẹ̀ sórí aṣebi, bí ààrá bá sán pa olè ní ìgbà mìíràn, wọ́n gbà pé Ṣàngó yóò gbé ohun tí olè yẹn jígbé lé e láyà. Gbogbo èniyàn yóò sì fi ẹni náà ṣe yẹ̀yẹ́. Èyí yóò mú ẹ̀rù ba gbogbo ìlú. Pàtàkì fún ààbò ilú ni Yorùbá ka àwọn òrìṣà wọn sí.

**Èèwọ̀**

Ohun pàtàkì mìíràn tó n mú kí àlááfíà àti ààbò wà lórí ìlú ni èèwo. Olúkálùkù ìlú àti ilé ló ní èèwọ̀ tiwọn. Yorùbá kò fi ọ̀rọ̀ èèwọ̀ ṣeré rárá, ohun tí wọ́n bá pè ní èèwọ̀, a kìí ṣe é. Olóyè Adégbóyèga Ṣóbándé sọ pé:

> Ọgbọ́n mẹ́ta pàtàkì ni àwọn tó ṣè wá sílẹ̀ dá nígbá tiwọn, láti máa fi tún ayé ṣe. Òun ló mú kí ètò, ẹ̀tọ́ àti àjẹpẹ́ ayé wà fún wọn. Ọgbọ́n kìnni ni ìṣèlú, ọgbọ́n kejí ni àṣà, ọgbọ́n kẹta sì ni èèwọ̀.

Àyọlò yìí fi ìran Yorùbá hàn bí ìran tó ní ọgbọ́n àti ìmọ̀-ìjìnlẹ̀-èrò tó ga fún ọ̀rọ̀ ìṣèlú àti ohun máyégún. Èyíkéyìí tí kò wọ̀, tí kò dára, láti hù ní ìwà ló n jẹ́ èèwọ̀. Ohun tí kò wọ̀ níí jẹ́ èèwọ̀.

Oríṣìíríṣìí ni èèwọ̀; èèwọ̀ àìsàn, èèwọ̀ awo, èèwọ̀ ìbínibí, èèwọ̀ kan-n-pá tàbí ọ̀ran-an-yàn, èèwọ̀ amẹ́mìígùn àti èèwọ̀ amáyégún. Pípa àwọn èèwọ̀ yìí mọ́ jẹ́ orísun ààbò àti àlàáfíà ní ilé àtí ìlú Yorùbá. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, ọ̀kan nínú èèwọ̀ àlàáfíá ni pé ‘‘A kìí jẹ ejò torítorí’’ Ọgbọ́n púpọ̀ wà nínú èèwọ̀ yìí. Ìdí ni pé, gbogbo oró ejò, orí ló wà. Bí ẹnìkan bá sì jẹ orí ejò tí eegun ejò

bá ṣèèṣì gún lẹ́nu tàbí tó bá há a lọ́fun, ọ̀run lẹ̀rọ̀. Èèwọ̀ mìíràn ni pé Ìjàkùmọ̀ kìí rìn lọ́sàn-án, ẹni abíire kìí rìn lóru. ‘‘Èèwọ̀ káyé-dára’’ ‘‘ká-má-yé-gún’’ ni èyí. Nílẹ̀ Yorùbá, ẹni ta bíire, ọmọlúàbí ènìyan kìí rìn lóru. Jàgùdà, olè, ọ̀mùtí àti àwọn yan-àlè-yan-àlè ló máa ń rìn lóru.

Èèwọ̀ mìíràn tún ni òwe yìí pé; ‘‘Òtòṣì ẹ̀gbọ́n níí jogún àbúrò, olórí burúkú baba níí jogún ọmọ’’.Èèwọ̀ amúlégún, amúlétòrò ni èyí. Èèwọ̀ pọ̀ jańtirẹrẹ, ó sì yàtọ̀ láti ìlú kan de ìlú kejì. Ìdí èyí ni wọ́n fi máa ń sọ pé; ‘‘Báyìí là n ṣe nílé wa èèwọ̀ ni ní ibòmíràn. Pípa èèwọ̀ mọ́ máa ń jẹ́. kí ìlú tòrò, kí ó sì ní ìsinmi.

## Ìfaradà Ẹ̀sìn

Bí ẹ̀jẹ̀ ti jẹ́ kò-ṣeé-má-nìí fún ara, bẹ́ẹ̀ ni ẹ̀sìn jẹ́ nínú àṣà àti ìṣe Yorùbá. Yorùbá ní ìgbàgbọ́ tó kira nínú Ọlọ́run. Wọ́n gbà pé ohunkóhun tí wọ́n bá ń ṣe láyé tí kò bá sí tỌlọ́run níbẹ̀, ohun náà kò lè ṣe àṣeyọrí. Wọ́n ní ìgbàgbọ́ nínú àwọn ọ̀kànlérínwó irúnmọlẹ̀ tí wọ́n jẹ́ alàgàta láàrin àwọn àti Ọlọ́run. Wọ́n gba ọ̀rọ̀ Ifá gbọ́ pé: ”Rírú ẹbọ níí gbe ni, àìrú ẹbọ kìí gbènìyàn”. Gbogbo òrìṣà ni wọ́n kà sí pàtàkì tí wọ́n kìí sí káàárè láti rúbọ sí wọn bó ti tọ́ àti bó ti yẹ. Ìgbàgbọ́ Yorùbá nínú àwọn òrìṣà wọn jinlẹ̀. Ó sì dá wọn lójú tó bẹ́ẹ̀ tó jẹ́ pé nígbà tí wọ́n kó wọn lẹ́rú lọ sí Brazil àti Cuba, wọn kò sọ ẹ̀sìn wọn nù. Pieere Verger (1960:113) jẹ́rìí sí èyí. Ó sọ pé:

> *In Bahia, the former capital of Brazil the descendants of South-West Nigerian have continued to worship their ancestral gods, or orisa to this very day, in spite of time and distance which separate them from their place of origin. This is also true of Cuba wherethe traditions of divination by Ifa are admirably preserved.*

Àyọlò yìí fi ẹsẹ̀ rẹ̀ múlè pé máyàmí ni àwọn Yorùbá pẹ̀lú ẹ̀sìn wọn. Wọ́n gbàgbọ́ pé aláàbọọ̀, olùpamọ́ àti olùpèsè ni àwọn òrìṣà wọn. Bí òrìṣà wọn bá sì ti pọ̀ tó nínú ilé àti ìlú ni ààbò wọn pọ̀ tó. Nítorí náà wọn kò yan òrìsà kankan ní ìpọ̀sì. Gbogbo wọn ló wúlò fún ohun kan tàbí òmíràn. Kódà Ẹ̀ṣù láàlù tí ẹ̀sìn àtọ̀húnrìnwá kà sí kìkì ibi, kìkì ìkà, kò rí bẹ́ẹ̀ nínú ẹ̀sìn àti ìgbàgbọ́ Yorùbá.

Èyí ló fà á tó fi jẹ́ pé nínú ilé kan, òrìṣà lè tó mẹ́ta tàbí mẹ́rin. Baálé ilé lè jẹ́ Onífá àti Ológùn-un, ki àwọn ìyàwó rẹ̀ sì máa sin Òrìṣà nlá, Ọya àti Erinlẹ̀. Kò sí ọ̀kan tó pa èkejì lára. Lójú tiwọn, ọ̀pọ̀ irú kò ba ọbẹ̀ jẹ́. Àjọṣepọ̀ tó dùn sì wà lásìkò tí olúkálùkù wọn bá ń ṣe ọdún òrìṣà wọn. Gbogbo ilé yóò sì máa dùn mọ̀ràn-ìn-mọran-in. Ní ìlú Òkuku ní Ìpínlẹ Ọ̀ṣun, Ìdílé kan ló ń sin Òrìṣà-oko. Ọ̀pọ̀ àwọn ènìyàn yóò sì jẹ iyán Òrìṣà-oko ni àjẹgbádùn. Èyí já sí pe ìfaradà ẹ̀sìn fẹsẹ̀ múlẹ̀ gbọn-in gbọn-in ní ilé, àdúgbò àti ìlú.

Síwájú sí i, ó fẹ́rẹ̀ má sí ìlú Yorùbá tí kò ní òrìṣà àjọbọ, tí wọ́n sì máa ń ṣe ayẹyẹ fún wọn ní ọdọọdún. Àpẹẹrẹ ni ọdún Edì ní Ilé-Ifẹ̀, Ṣàngó ní Ọ̀yọ́, Òkèèbàdàn ní Ìbàdàn, Ògún ní Òǹdó, Ọ̀ṣun ní Òṣogbo, Olóòkù ní Òkukù, Ògìyán ní Èjìgbò Òrìṣà Pópó ní Ògbomọ̀ṣọ́ abbl. Gbogbo ọdún òrìsà wọ̀nyí, àjọṣe ní fún gbogbo ará ìlú. Ní ọjọ́ àkàrà Olóòkù ní Òkukù, ilé kọ̀ọ̀kan ni yóò dín àkàrà tí wọn yóò gbe lọ sí igbó Olóòkù. Àjẹtì ni àkàrà fún gbogbo ìlú lọ́jọ́ náà. Lọ́jọ́ àṣekágbá ọdún Olóòkù, tonílé tàlejò ni yóò jó yí ìlú ká, gbogbo lọ́balọ́ba, ní ìjọba ìbílẹ̀ Odò-Ọ̀tìn, àwọn bíi Olúnísà Ọlọ́yàn-an, Onígbàyè, Àlàkọ̀ọ́sùn, àti àwọn Ọba ńlá ńlá bíi Akìrun ìlú Ìkìrun, Olóbùú ti ìlú Ìlobùú, Àtaọ́ja ìlú Òṣogbo ni yóò wá bá Olókukú ṣe ọdún Olóòkù. Gbogbo onílù tí ń bẹ ní ìjọba ìbílẹ̀ Odò-Ọ̀tìn ni yóò péjọ sí Òkukù. Ìdùnnú yóò sì subú layọ̀ káàkiri ìgboro.

Bẹ́ẹ̀ ló máa ń rí ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìlú ní ilẹ̀ Yorùbá. Kìí tilẹ̀ ṣọ̀rọ̀ ìfaradà ẹ̀sìn ni ti àwọn Yorùbá, àjọṣepọ̀ ni. Èyí ló mú àlàáfíà àti ìṣọ̀kan bá ìlú. Ẹ̀sìn kò dí ìgbéyàwó lọ́wọ́, ọmọ bàbá Ọlọ́ya le fẹ́ ọmọ Oníṣàngó. Ológùn-ún le fọmọ fún Ọlọ́ṣun. Bàbá Ọlọ́dẹ le fi ọmọ rẹ̀ fún Mùsùlùmí tàbí Ọmọlẹ́yìn Kírísítì. Bó bá di àsìkò ìgbéyàwó, gbogbo wọn ni yóò péjú pésẹ̀ fún ayẹyẹ ìgbéyàwó. Bí ọ̀rọ̀ pàtàkì bá ṣẹlẹ̀, kò sí ẹ̀sìn *kankan* tó gbọ́dọ̀ dí ẹnikẹ́ni lọ́wọ́ láàrin mọ̀lẹ́bí fún àpérò àti àṣàrò. Gbogbo nǹkan wọ̀nyí ló máa ń

mú ìlú tòrò, tó sì mú ìfẹ́ àti àlàáfíà bá ìgbárá àti ìgboro. Ó sì jẹ́ okùnfà ìṣọ̀kan àti ìtẹ̀síwájú fún orílẹ̀-èdè Yorùbá.

## Àgbáløgbábọ̀

Àbáyúnàbábọ̀ gbogbo atótónu yìí ni pé nínú àṣà, ìṣẹ̀ṣe àti ìṣèlú Yorùbá, ohun púpọ̀ ni a le ṣàmúlò fún ìtẹ̀síwájú àti ìdàgbàsókè orílẹ̀-èdè Nàìjíríà. Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a pe àkíyèsí sí ohun méta pàtàkì tí àwọn baba-ńlá wa, àwọn tó ṣẹ̀ wá sílẹ̀ fi ẹsẹ̀ rẹ̀ múlẹ̀ lórí ọ̀rọ̀ ààbò àti ìfaradà ẹ̀sìn. Èkínní ni èdèyedè, èkejì ni ìgbésí ayé ọmọlúàbí, ẹ̀kẹta sì ni òtítọ́-inú.

Lórí ọ̀rọ̀ ààbò àti ìfaradà ẹ̀sìn, èdè wọn yé ara wọn – èdè Yorùbá. Èdè Yorùbá ni wọ́n fi ń ronú. Èdè Yorùbá ni wọ́ń fi ń sọ̀rọ̀. Éde Yorùbá ni wọ́n fi n gbé ìgbésẹ̀. Èyi ló mú kí wọ́n ṣe àṣeyọrí-sí-rere. Ẹ jẹ́ kí á ṣe é bí wọ́n tií ṣe. kò lè rí bíí tíí rí. Mo ké sí gbogbo àwọn ọ̀mọ̀ràn, gbogbo àwọn Ọ̀jọ̀gbọ́n, gbogbo àwọn oníṣẹ́ ọwọ́, oníṣẹ́ oṣù, òṣìṣẹ́ ìjọba, ẹ̀yin ìyálọ́jà. mo ké sí gbogbo àwọn Gómìnà ilẹ̀ Yorùba, àwọn òṣèlú ilẹ̀ Yorùbá, kí wọn dá èdè Yorùbá padà sí ilé wọn. Ò dára kí àwọn Gómìnà àti aláṣẹ ìjọba dá èdè Yorùbá padà sí ilé-ẹ̀kọ́ láti nọ́sírì dé Yunifásitì.

Nìgbà tí Olóyè Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ n ṣe olórí ìjọba ilẹ̀ Yorùbá, èdè Yorùbá gbilẹ̀ gboko. Gbogbo ilẹ̀ Yorùbá títí dé Lọ́kọ́ja, Kàbà, Ògòrì- Màgóngò, Benin, Ṣẹ̀kírì, Warri, abbl; èdè

Yorùbá lo gbilẹ̀ ní Ilé-ìwé wọn. Ní báyìí, púpọ̀ àwọn ọmọ Yorùbá kò lè sọ tàbí ka èdè Yorùbá. Mo kà nínú ìwé ìròyìn kan pé láti ìbẹ̀rẹ̀ sáà yìí lọ, wọn yóò máa fi èdè *China* kọ́ àwọn ọmọ ní ilé-ẹ̀kọ́ ní ìpínlẹ̀ Èkó.

Àgbẹdọ! Bí èyí bá fi rí bẹ́ẹ̀, àkóbá nlá àti ìfàsẹ́yìn burúkú ni yóò mú bá ìdàgbàsókè ilẹ̀ Yorùbá. Àwọn Gómìnà, àwọn aláṣẹ ètò èkọ̀, gbọdọ ṣe ojúṣe wọn nipa dídá ìwé kíkà Aláwíyé ti J.F Ọdúnjọ, ìwé ìtàn àròsọ D.O. Fágúnwà ìwé Ọládẹ̀jọ Òkédìjí, Adébáyọ̀ Fàlétí, Akínwùmí Ìsọ̀lá, abbl pádà sí ilé-ẹ̀kọ́ alàkọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ títí dé yunifásitì kí wọn sì sọ ẹ̀kọ èdè àti àṣà Yorùbá di kàn-ń-pá ní gbogbo ilé-ẹ̀kọ́ ní ilẹ̀ Yorùbá. Ìwé ìròyìn *Aláròyé* ọjọ́ kejì, oṣù kẹwàá, 2012 tẹnu mọ́ ọn pé ohun àbùkù ni kí ọba máa sọ ní gbangba pé édé Yorùbá kò dàn mọ́rán lẹ́nu òun àfi èdè òyìnbó. Irú ọba bẹ́ẹ̀ kò yẹ fún ipò ọba ilẹ̀ Yorùbá.

Èkejì, láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀, ìran Ọmọlúàbí ni a mọ ìran Yorùbá sí, Ìwà yìí náà ni a sí rí nínú ìhà tí wọn kọ sí ọ̀rọ̀ ààbò àti ìfaradà ẹ̀sìn, bí a ti si láwẹ́láwẹ́ nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí Ẹ jẹ́ ká ṣe é bí wọn tií ṣe é, kó lè rí bíí tíí rí. Gbogbo òbí àti alágbàtọ́, gbogbo ọ̀tọ̀kùlú, Ọba àti ìjòyè, Gómìnà, Olóṣèlú, Olùkọ́, Ọlọ́pàá, Sọ̀rọ̀sọ̀rọ̀, Òṣèrè, Òṣìṣẹ ilé-iṣẹ́ Rédíò àti Tẹlifísàn, oníweéìròyìn, Oníwàásù àti Oníwáàsí, ó yẹ kí á polongo ìwà ọmọlúàbí ní ilẹ̀ Yorùbá. Ó tọ́ kí á padà sí orúkọ ọmọlúàbí tí ìwà ọmọlúàbí tí a mọ̀ wá sí láti òwúrọ̀ ọjọ́. Ẹ jẹ́ kí àwọn ènìyàn máa wo eré tó fi ìwà ọmọlúàbí

hàn lórí tẹlifísàn ilẹ̀ Yorùbá. Àkóbá burúkú ni eré dọ́kọdọ́ko, gbọkọgbọkọ, jẹgúdúragúdú, olè, apànìyàn, jàgídíjàgan ń ṣe fún àwọn ọ̀dọ́ wá. A gbọdọ̀ jẹ́ kí àwọn ọmọ wa mọ ire tí ń bẹ nínú ìwà ọmọlúàbí híhù kó sì yé wọn pé "ire níí gbe ni, ìkà kìí gbènìyàn".

Ẹ̀kẹta, nínú àlàyé tí a ṣe saájú, ọ̀kan nínú ohun tó jẹ́ kí ọ̀rọ̀ ààbò àti ìfaradà ẹ̀sìn yọrí sí rere fún wọn ni pé, òtítọ́-inú ni àwọn Ilé, àdúgbò àti ìlú fi mú ọ̀rọ̀ náà. Wọn ní ìfojúsùn tó lágbára. Ọ̀rọ̀ ààbò àti àlàáfíà ìlú jẹ wọ́n lógún. Ìpinnu wọn sì ni pé, kójú má rí, ibi, gbogbo ara loògùn rẹ̀. Oníbodè, Alóre, Amí, Ọba, Ìjòyè, Olórí Awo, Olórí Ọdẹ, gbogbo ọdẹ àti àwọn ènìyàn bíi Aládòkun Ìyàndá, òtítọ́-inú pẹ̀lú ọkàn kan ni wọ́n fi n ṣe iṣẹ́ ààbò àti aláàfíà ìlú. Wọn n ṣé tinútinú, wọn ò purọ́ fún ara wọn. Lónìí, a ní àwọn aṣọ́bodè Amí, Alóre àti onírúurú Agbófinró. Àmọ́ gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀ òǹkọ̀wé Olú Owólabí "Ìjàǹbá ṣèlú, Olórí-olè ló ń ṣọ́ ìgboro". Bí a bá fi ojú sùnnùkùn wo ọ̀rọ̀ àwọn olóṣèlú wa, wọn kò tẹ̀lé òtítọ́-inú bíi ti àwọn baba nlá wa. Ọ̀rọ̀ wọn ti di:

Irọ́ ń purọ́ fúnrọ́,
Ṣìgìdì ò lẹ́nu, ó lóun yóò fọhùn
Irọ́ ń purọ́ fúnrọ́,

Ọ̀rọ̀ wọn dàbí ọ̀rọ̀ Adébáyọ̀ Fálétí nínú *Báṣọ̀run Gáà*:

Kọ̀lọ̀kọ̀lọ̀ ń ṣọ̀rẹ́ híọ̀híọ̀ ,
Àwòdì ń bádìẹ ṣọ̀rẹ́,
Aáyán ń fọmọ ṣọ̀fà fádìẹ;
Irọ́! Irọ́ ni wọ́n ń pa fún'ra wọn.

Ẹ jẹ́ kí á tẹ̀lé ìlànà òtítọ́-inú tí àwọn baba-nlá fi ṣe ọ̀rọ̀ ààbò àti ìfaradà ẹ̀sìn.

Ní ìparí, mo bẹ̀ gbogbo àwọn gbajúmọ̀, ọ̀mọ̀ràn, ọ̀mọ̀wé, òjọ̀gbọ́n àti àwọn ènìyàn pàtàkì gbogbo láti rántí ọ̀rọ̀ òsèré ilẹ̀ gẹ̀ẹ́sì n nì, Willian Shakespeare, tó sọ nínú eré rẹ̀ *Tragedy of Richard II;*

*My honour is my life,*
*Take honour away from my life,*
*And my life is done,*
*Therefore in honour I live;*
*And in honour I shall die.*

Ẹ jẹ́ kí á fi ìjìnlẹ̀ ọ̀rọ̀ yìí ró ara aṣọ, kí á sí gbé e wọ̀ bí ẹ̀wù. Ọ̀rọ̀ ààbò àti ìfaradà ẹ̀sìn ní orílẹ̀-èdè wa ti ń di;

Kò run ni,
Kò run ni,
Ó ń dòòyì ká ni o.

Boríborí gbogbo rẹ̀ ni pé, ìran Yorùbá kìí fi ọ̀rọ̀ àdúrà jáfara. Ẹ jẹ́ kí á gbàdúrà pẹ̀lú òtítọ́-inú àti ọkàn kan lórí ọ̀rọ̀ ààbò àti ìfaradà ẹ̀sìn. Àdúrà níí gbà, agbára kìí gbà.

## Díẹ̀ nínú àwọn iwe ìtọ́kasi

*Aláròyé*: Ìwé ìròyìn tó ń ṣojú ọmọ Yorùbá níbi gbogbo,ọjọ kejì oṣù kẹwàá,2012.

Crowther, M.(ed) (1960). *Nigeria Magazine.*

Fálọlá Tóyìn (2012). *Atlantic Yorùbá and the Expanding Frontiers of Yorùbá Culture and Politics. University of Texas at Austin, U.S.A. 2012 J.F Odunjo Memorial Lecture, Ibadan; Ibadan Cultural Studies Group.*

Ògúnṣínà B. (2006). *Sociology of the Yorùbá Novel:* Ilorin: Integrity Publication.

Ọlájùbú O. (1981). *Ìwé Àṣà Ìbílẹ̀ Yorùbá*. Lagos: Longman Nigeria Ltd, Ibadan.

Ọlátúnjí (1996). Yorùbá History, Culture and Language. Ìbàdàn: University of Ìbàdàn Press.